# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Adajọ ni ki ọlọpa-obirin san £49 pada fun ọkọ ti o fẹ ẹ sọna

ILESHA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Oloye D O A Oguntoye, Adajọ Kotu Ibilẹ (Grade "A" Customary Court) Ilesha ṣe idajọ pe ki ọlọpa-obirin kan, Josephine Ampighi (ti iṣe ibatan Ajanaku) ati baba rẹ Samuel Ampighi san pọnun mẹtadinladota (£47) fun ẹnikan, Dominic Magbai nitori adojo pọnun (£150) owo-idana ti o san le ọlọpa-obirin na lori ti o si pẹjọ rẹ si Kotu. Adajọ na si tun sọ pe ki Dominic ti o pẹjọ na san pọnun mẹrindinlogbọn ṣile marun (25 guineas) pada fun ọlọpa-obirin na nitoripe o gbe on ati baba rẹ ṣe wahala wa si Kotu nitoripe ẹjọ ti nwọn le pari rẹ nile ni.

Ọlọpa-obirin na ti rojọ tẹlẹ pe, nṣe ni Dominic tan on jẹ pe, ọrẹ on ọkunrin ti on ti nfẹ tẹlẹ jẹ alailera ti ko le ba obirin lopọ, ki on kuku ba on gbeyawo papọ, larin ibiti nwọn ti nro ẹjọ na lọ ni Dominic ba sọ pe on ko ṣe ẹjọ na mọ, Adajọ si sọ wipe, bi o ba ṣe wipe Dominic ko sọ pe on ko ṣe ẹjọ na mọ ni, nṣe ni on iba bu owo irinsẹ nla fun un ki on to tu ẹjọ na ka.

## Salami Balẹ komọjade

Abule Ọffa Ajilete.

LAIPẸ yi ni Ọlọrun fi ọmọ ibẹta ta Oloye Salami Balẹ ati iyawo rẹ l'ọrẹ, nwọn si ṣe suna awọn ọmọ na ni ọjọ kejọ, baba awọn ọmọ-titun na si fi onjẹ ati nkan mimu tẹ awọn alabaṣeyẹ ọjọ na l'ọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni: Ọgbẹni Solo Alaga, Salawu Pẹkun, Ramọnu Denja, Liadi Oluwo, Bello Olumọrin, Buraimoh Oshogbo, Alufa Lawani, Adamọ Oro, Sumọnu Ibitoye, Lawani Ikirun, Salami Okunlọla ati Alhaji Bello.

Ire a kari o.

## Aina di ologbe

ỌRIN-EKITI.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejila oṣu kẹwa odun yi ni Ọgbẹni S. J. Aina jalaisi, iṣẹ olukọni ni ologbe yi ti nṣe tẹlẹ ri ki o to gba isinmi (pension), o si jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ekiti ti o kọkọ bẹrẹ iṣẹ olukọni ni iwọn ọdun mokandinlogoji sẹhin ni agbegbe Ekiti. O to iwọn ọdun mẹfa nisisiyi ti o gba isinmi kuro nibi iṣẹ rẹ.

Gbara ti o ti ku ni ẹsẹ gbogbo awọn Alufa Ijọ Ṣọọṣi Methodist ni Agbegbe Ekiti ti pe sibẹ. Enia mẹwa ni Ọba Olojudo ti Iddo-Faborọ paapa ran wa si ibi isinku na. Gbogbo awọn enia ti nwọn wa si ibi oku na ni awọn ọmọ'loku fi ohun jijẹ ati mimu tẹ lọrun.

Diẹ ninu ogunlọgọ awọn enia ti o wa si ibi eyẹ isinku ọjọ na ti aye wa fun lati darukọ ni awọn: Alufa Jones, Alufa Babalọla, Baba Ẹgbẹ Ijọ Methodist Ifaki; Ọgbẹni Dada ati Ajaiyi, Olukọ-agba Ile-Ẹkọ awọn olukọni ni Ifaki.

## Oloye Oripẹlaiye ṣe iwuye

EPINMI-AKOKO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kẹwa ọdun yi ni Oloye Aliu Oripẹlaiye, Amulaka Epinmi-Akoko ṣe inawo iwuye oye rẹ ni ilu yi. Ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ, ẹbi ati awọn ojulumọ rẹ ni o pe ṣọṣọ sibi iwuye na, oriṣiriṣi ilu ati awọn elere ni o pe sibẹ pẹlu, irohin ko to afojuba ni, o buaiya o le gongo. Oloye na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia pataki ti o wa si ibi aṣeyẹ na ni awọn Ọgbẹni Ajidagba Afolabi, Yaya, Olupese, Yesufu Orunmọloye, Sunmọla, Abu Olofin ati Momọdu Sunmọh.

Oye a mori o.

## Igbeyawo John dun

IRORẸ LẸBA OMUARAN.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni John Adeyinka Tailor gbe omidan Abigail Moronfade ni iyawo alarinrin. Ẹyẹ ọjọ na buaiya, o le gongo, nṣe ni ọkọ iyawo ngnawo bi ẹlẹda.

Nigbati o di ọjọ iyin iyawo, awọn ẹgbẹ ọkọiyawo pẹlu aṣọ ẹgbẹjoda si bẹrẹ ere lati agogo meji ọsan titi ilẹ fi ṣu. Awọn onilu ọjọ na ni Bello Alabi, Raimi Boyeji ati Gbada Awọlumatẹ.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn aṣiwaju Ẹgbẹ Alabaṣeyẹ na ni Salawu Giwa, Israel Ogundele, Joel Adewunmi ati ọpọlọpọ ti ko si aye fun lati darukọ wọn.

Ẹhin iyawo ko ni mọ ẹni o.

## Adajọ sọ ẹniti o ji £200 ninu mọto ti o ṣubu si ẹwọn oṣu mejidilogun

ABẸOKUTA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Adajọ Kotu Ibilẹ (Ake Grade "A" Customary Court) Abẹokuta sọ ọdaran kan Jimọh Akanla si ẹwọn oṣu mejidinlogun nitoripe o ji owo bi igba pọnun (£200) ninu ijamba-mọto akẹru kan ti o danu larin ọna Ibadan si Abẹokuta.



# ỌRỌ AKEWI

**Lati ọwọ Ọmọ-ọba Akibu Alarape, Ibadan**

## ...nu Araiye L'ẹbọ

AGO o'nle o, Olotu, karaole o,
Ẹsin ọrọ wa toni fo fẹ rẹ rẹ, o dori ẹnu,
Pagidari, igida! wọn ni ẹnu-araiye l'ẹbọ,
ogẹdẹ ki i ha ni lọrun, ẹnu-araiye l'ẹbọ,
ẹnu o! ẹnu o!! ẹnu o!!!; Kaasa!

### NWỌN NI ẸNU OFORO NI I PA OFORO

Ẹnu oforo ni i pa oforo,
on lo difa fun oloforo nijọ ọjọ-kini,
nigbati o bimọ meji ti o ni gbogbo ile on kiki ọmọ,
aṣe, nitotọ ẹni ẹnu ba pa ti ko ku,
eleyini ko ni i jẹ araiye, ko ni i jẹ ero ọrun,
ẹnu l'ọmọ-araiye fi npe igi ti o fi nwo,
ẹnu l'omọ-araiye fi npe ogun ti nwọn fi nrogun,
ẹnu l'omọ-araiye fi npe ọtẹ. nwọn a si ri ọtẹ,

Aṣẹṣẹ-daiye Ijimere nijọ ọjọ-kini
kẹlẹkẹlẹ ni nwọn dudu bi aro,
ẹnu ọmọ-araiye lo sọ 'Jimere di pupa,
ẹnu l'ọmọ-araiye fi npe Adegun,
ẹnu ọhun na ni ọmọ-enia fi npe Adeogun,
ẹnu ọmọ-araiye ko duro lojukanṣoṣo,
e ma gbagbe o,
nwọn ni, nwọn pe, l'ọrọ ẹnu ọmọ-araiye

### NWỌN NI B'OJU RI ẸNU A DAKẸ

Ọrọ ṣoro o sọ!
nitotọ, ọgọ ẹlẹgbara dun un dana,
ọgọ ti Ṣọpọnna si dun un roka,
bẹ ẹ si ni, ọwọ ba tẹ Ibeji, iṣu yio jinna
ṣugbọn ẹ ma gbagbe o,
ọjọ-atisun l'ẹbọ.
ẹni ọrọ ba ya lẹnu lẹkan ri,
eleyini ko ni sanṣọ bẹ ẹ ṣ'oro mọ lailai,
ẹ ṣe pẹlẹ o.

Ẹni abire ko gbọdọ fi gbogbo ẹnu sọrọ jakata,
nwọn ni ọrọ ẹnu ni i yọ obi ninu apọpọ,
ọrọ ẹnu ọmọ-enia na ni i yọ ida ninu akọ,
gbolohun kan ọrọ a ma a da ogun silẹ latijọ,
nitotọ, ogun kan ko si mọ lode toni,
ṣugbọn ẹ ma gbagbe o,
gbolohun oro kan ko ṣaile da gbogbo ilu laamu tile-toko
Edumare ma jẹki a ṣi wi, ma jẹki a ṣi sọ."
Nwọn ni bi enia ko lowo, a ni enia,
bi bẹ ẹ si kọ, a si lọro rere lẹnu,
nwọn ni, bi iwọ ba jẹ ẹni-rere, bi o ko jẹ ẹni rere
sa tilẹ sọ oro ẹnu rẹ ki a gbọ,
nitori ọrọ ni a fi ngmọ iyatọ enia,
larin ọmoluabi ati ọmọlangidi;
awọn arigi-denia.

Wo oju ewe kẹfa

# Arugbo meji ja ehın ọkan yọ

EBUTE-MẸTTA.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni awọn ọlọpa mu baba agba kan, Buraimọh Ọlaogun, ẹni adọrin ọdun (70 years) wa si iwaju Adajọ Kotu Kekere ti Ebute-Mẹtta fun ẹsun pe o ba ibatan rẹ kan, Mọriamọh Ashabi, ẹni ọgọrin ọdun (80 years) ja, o si ka ehin rẹ kan ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o koja yi.

Nigbati ọdaran na rojọ, o ni on ko jẹbi, Adajọ ni ki nwọn fi igba pọnun (£200) gba iduro fun un, o si yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹdogun oṣu ti o mbọ yi. Bi nwon ba ti pari ọrọ na si ẹ o tun ma a ri i ka ninu iwe wa o.

## Awọn dana-dana dena de Shawcross: nwẹn lu u

GENEVA.

NI alẹ ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni awọn dana-dana mẹta lọ dena de Ọgbẹni Christopher Shawcross, Q.C., ẹni ọdun mẹrinleladọta, aburo Ọlọla Shawcross, Alaga Provisional Institute of Space Law, nwọn lu u nwọn si da ọgbẹ si i loju ọtun rẹ ati awọn ibomiran lara rẹ pẹlu, igbọn rẹ si wa ṣugbọn nwọn ko ṣe e leṣe pupọ.

Ọgbẹni Christopher Shawcross Q.C., ni dajudaju awọn dana-dana fẹ lati ko on lẹru ni. O ni irufẹ ijamba bayi ti ṣẹlẹ si aya on ri ki i si ṣe ẹkan ṣoṣo mọ. O ni nwọn ti lu on ni Malaya ati ni Naijiria laipẹ ọjọ. o si ṣe alaye pe igi kan ti ara san pa, diẹ ni o ku ki o kọlu mọto-ayọkẹlẹ kan ti on ngunlọ nigbakan.





ṢỌRA FUN

OTUTU IBA




DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Olotu, ẹ karọ sa

OLOTU—Ẹ ma a wolẹ

ALAPARA—Ewo ni ẹ fẹ ki ngmu ṣe ni owurọ yi •

OLOTU—Mimuṣe bawo?

ALAPARA—Mo ṣe bi ibikan ni a fi ọrọ ti si.

OLOTU—Ṣe ọrọ Sariyu Rọtikatika ni o tun gbe wa ti a o ji ko si ni arọ yi?

ALAPARA—Ọro ti Sariyu na ko to itan kọ?

OLOTU—Mo ngbọ, bẹrẹ si sọ ọ

ALAPARA—Nibiti mo gbe ọro mi de nipa ti Sariyu ni ọsẹ ti o kọja ni pe "nigbati o pada lẹhin ọkunrin ti nwọn pe ni ọkọ rẹ, ti mo si bi i lere o si sọ fun mi pe Kọsini on ni, ti o ti ṣe kilọkilọ fun ni pe ki njawọ ninu majẹki-eti-ẹni-odi ti ki i jẹ ki inu ẹni o dun" ni mo ba ọrọ na de ti ẹ fi sọ fun mi pe ki nṣe gafara fun nyin, nitorina lati ibẹ na ni ngo si bẹrẹ orọ ni sisọ fun nyin lọsẹ yi.

OLOTU—Ọraiti, ma a sọ ki a gbọ.

ALAPARA—Nigbati o to nkan bi oṣu mẹta ti a ti nfe ara wa ni Sariyu pe mi pe, njẹ ko to ki nlọ mọ awọn enia on, mo si bi i lere pe nibo ni nwọn gbe wa? O ni ni Saro ni. Mo bi i lere pe ṣe ọmọ Yoruba ni ọ, o ni nitoto ọmọ Yoruba ni on ṣugbọn ni Saro ni nwọn gbe bi on si. Mo tun rọra bi i lere pe Yoruba ilu tibo ni tinyin, on na si bi mi pe Yoruba ilu ibo ni temi na. Mo si da a lohun pe ti Ibadan ni. Ṣe iwọ na ngbọ ti a ba de otẹli ti gbogbo awọn enia i ma sa mi pe Alapara Ibadan lọtun losi.

O tun wa bi mi lere pe njẹ Alapara Ibadan ni oruko ti baba ati iya sọ ọ ni ọjọ ti nwọn ko o jade, mo si da a lohun pe orukọ nagijẹ kan ni Alapara Ibadan Akanni Ajibọrọde ni orukọ abisọ mi, o ni kini orui baba mi mo si da a lohun Ajibohun lorile Ijaiye. O ni iyẹn ni pe Misita Akanni Ajibọrọde Ajibohun ni orukọ rẹ gan an, mo ni bẹni, ni o ba fi npe mi ni "A Sikua".

Ka ma fa ọrọ gun lọ titi mọ, o ni ki mba on lọ mọ awọn enia on ni ilu Saro. Owo ti a fi ṣe ipalẹmọ le ni igba pọnun. Nigbati a de ilu Saro a wọ si Otẹli ti awọn ọlọla i ma a de si. Nigati a de ibẹ ni o to ṣẹṣẹ sọ fun mi pe on ko kọ iwe si awọn enia on tẹlẹ nitorina on nlọ sọ fun nwọn pe o de pẹlu bale on.

O ni ilọ ti on yio lọ yi on ni lati fara-han pe ọlọla ni ọkọ on ni mo ba fun un ni ọgọrun pọnun. Nigbati o jade lọ, ọjọ karun ni mo to fi oju kan an, aṣe e mo mu u lo f'awọn ọkọ-atijọ rẹ ni, dide ti yio de ni ọjọ karun ọkunrin mẹfa ni o ba a de si Otẹli na.

Ko tun jẹ abọ awọn obi rẹ fun mi mọ nṣe ni o bẹrẹ si juwe awọn enia wọnyi fun mi ni ọkọọkan bi nwọn ti jẹ pataki to ni ilẹ Saro, ti o si nfi emi paapa han pe onișowo-nla kan ni mi lati Naijiria talẹ-taro ni awọn enia fi npara ọdọ mi. owo ti mo si na fun wọn koja igba pọnun fun oriṣiriṣi onjẹ adidun ati ọti olowo giga lojojumọ.

Ti a ba fẹ sun lalẹ ti mo ba bere pe, ewo ni o ba bọ ọdọ awọn obi rẹ? A si sọ fun mi pe on ti yo fun ọti, afi bi oju on ba walẹ ni on o to fun mi ni esi, ti ilẹ ba si ti mọ ni awọn ọkunrin wọnyi yio ti de ti a o ti bẹrẹ faaji.

Nigbati o to bi ọsẹ kan ni o to sọ fun mi pe awọn ọkunrin wọnyi ti on ba ṣe alabapade kọ fun on laye ki on de ọdọ obi on, o ni bi enia ba si fi oju tinrin iru awọn Ọlọ/la bẹ ẹ, ẹtẹ ni yio ba jade ni ilu. Ọrẹ rẹ wa su mi, ewo ni a ba wa, ewo ni a wa de ilu ba? Sariyu wa di egun-ẹja, nṣe ni o ha mi ni ọna ọfun.

Aṣe kekere ni mo ṣẹṣẹ nri yi, ẹni sọ ile nu sọ apo iya kọ. Nṣe ni o tun da ọjọ miran fun mi pe on nlọ sọdọ awọn obi on, mo si kilọ fun un pe ibẹ ni ki o lọ taara. Nigbati o jade ti o di ọjọ kẹrin ni o sunkun wọle, o ni on lọ ta orire, nwọn jẹ ọgọrun mọ on lọwọ itiju eyi ko jẹki on le yọju si awọn obi on mọ.

Nigbana ni mo họra-kuru-kuru ni mo tun gbe ọgọrun pọnun miran fun un, bi o ti tun ṣe ọgọrun pọnun na si, ma a sọ fun nyin ti o ba di ọsẹ ti o mbọ. Olotu nko sa da nyin lagara pẹlu ọrọ mi yi?

**OLOTU—Mo ri i pe arikọgbọn wa nibẹ ni mo ṣe nfi ibaralẹ gbọ ọrọ rẹ, ti o ba di Satide ti mbọ ki o tun wa.**

ALAPARA—Ẹ ṣe pupọ, o digba-o-ṣẹ.



# AKIYESI

**Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe ti ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.**

**OLOTU**

## Lemọmu Lawani di ologbe

AKIM ỌDA, GHANA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu kẹwa odun yi ni Ọgbẹni Lemọmu Lawani Asunmọ jade laiye, nwọn sin oku rẹ gẹgẹbi eto ti awọn Imale. Alhaji Musitafa lati Kwayako pẹlu Alufa Raimi Akewuṣọla lo ṣe wasi l'ọjọ na. Awọn ọrẹ ati ọmọlẹbi ologbe na fi jijẹ ati mimu tẹ awọn ti o wa si ibi isinku na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Lawani Oloyede, Buraimọ Tailor, Gbadamọsi, Ọkunọla Bello, Sanusi Arilẹṣẹ, Joseph Idowu, Buraimọ Adebinpe, Sunmọnu Adefẹmi, Bakare, Sulle, Iyaafin Asimọwu Ọlalonpe, Humani Abẹọ ati Serah Ọlaọrẹ.

## Ikore Ṣọọṣi Ilișan dun

ILIṢAN RẸMỌ.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni awọn agba Ijọ Ṣọọṣi Barnaba Mimọ (CMS) ṣe Isin Ajọdun Ikore wọn. Isin Ikore na bẹrẹ ni ago mẹwa owurọ ṣugbọn ki to bẹrẹ ni ẹsẹ awọn ọmọ ilu Ilișan ti nwọn wa l'ẹhin odi bi, Abẹokuta, Eko, Ibadan ati Accra ti pe si Ṣọọṣi na ni ẹkun rẹrẹ.

Alufa Ẹni-ọwọ E A Falaṣẹ lati Ṣọọṣi Ikẹnnẹ l'oṣe iwasu ọjọ na. Lẹhin Isin awọn Ijọ si fi nkan jijẹ ati ohun mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ajọdun na lọrun. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ara idalẹ ti nwọn wa si ibi isin-ikore na ni: Ọgbẹni J. F. Oṣibọdu, Nat. O Oyename, A O Babayeju, F A Adetayọ, C O Metilelu, D A Ṣogbanmu ati M S Afuyẹ.

Aṣeyiṣamọdun o.







## AKIYESI PATAKI

... Circulation Manager, Amalgamated Press Ltd., P. O. Box 143 Lagos Nigeria ...

OLOTU.

* * *








Awọn Oloye meji lati inu ajọ Igbimọ awọn Oloye Ipinlẹ Iwọ-Orun wa ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ fun idagbere rẹ fun Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun kikuro ti yio kuro nibẹ lọhin idibo iwọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria.




## ITAN KUKURU OLOWE

### Lati Ọwọ Oluṣẹgun Ige, Agege

### Ọba Ti Ko Mọ Ọlọrun

ỌBA TI KO MỌ ỌLỌRUN

## Ilu Ire nfẹ omi ẹrọ

Ki Oluwa tubọ mu a ran ...

Emi ni,
J. O. ỌLADOJA

## Ibere ati idahun

Daniel Ọlaniyọ, Shomolu.

Idahun si ibere ake yi.

OLOTU.








# Aworan emi Erukobodo niyi

EMI "Ẹrukobodo" dupẹ lọwọ ẹnyin onkawe, ti ẹ ni inu didun lati ri aworan mi fun asọyanju ọrọ mi ninu "Irohin Yoruba. Oluwa Ọba Olodumare ko ni da nyin pada sẹhin, ibukun ati alafia yio si ma a ba nyin gbe titi lai.

Awọn baba wa ma a npa lowe wipe:—"Ẹni riri, ko jọ eni mimọ". Aworan mi yi yio han si ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe wipe, emi Erukobodo ko fara mi pamọ fun ẹnikẹni ninu ilẹ Naijiria, nilẹ Farase ati ni nilẹ Ghana rara, ṣugbọn, bi ẹ ti mo mi si ni o yatọ ati wipe, emi paapa fi ara mi han yin gẹgẹbi owe kan ti awọn baba wa ma a npa wipe:—Bi enia ko ba ṣe bi Ẹlẹdẹ ni'gbo Ijẹbu, oluwarẹ ko ni dabi Egun Adegborọ l'ọja ọba. Ki owe na o jẹ ti ẹnyin onkawe.

**WOLI ATATA NI ANIYI**

Mo ti lero wipe, nko ni sọ inkankan ju eyiti mo ti sọ ṣiwaju yi lọ, ṣugbọn, bi mo ba da ẹnu durọ ni alai ko fesi si ọrọ Woli S Aniyi, ọrọ na yio dabi ọrọ ẹniti a ṣe l'ore ti ko dupẹ, nipa bayi emi Ẹrukobodo dupẹ lọwọ Woli Aniyi (Awo Irawọ) mo si tun dupẹ lọwọ Ẹlẹda mi pẹlu, ki Oluwa ki O jẹki igbesi aiye gbogbo wa jẹ rere.

Gẹgẹbi Irawọ mi ti o han si Woli Aniyi, ti o sọ ọ fun agbaiye ninu "Irohin Yoruba" wipe, a bi Ẹrukobodo ni ọjọ Ọjọbọ (Thursday) bẹ ẹ ni ọrọ na ri, adura mi si alaye Irawọ na ni wipe, ki Oluwa ki O jẹki Irawọ na ṣe bẹ ẹ fun t'ọmọde t'agba wa.

**ỌMỌ-ỌBA NI ẸRUKOBODO**

Eyi ni ohun ti Woli Aniyi nfẹ ki nsọ fun agbaiye, boya Irawọ mi ti Oluwa fi han on ko ribẹ:—Emi Ẹrukobodo jẹ ọkan ninu idile Ọba Adelẹkan ti ẹ mọ adape oruko rẹ nigba aiye rẹ ni Ọba Olubuse, ni igboro ilu Ile-Ifẹ, a bi mi ni ọjọ Alamisi (Thursday) ni deede agogo mẹfa owurọ ni ọjọ kẹjọ oṣu kẹfa ọdun 1904, oruko abiso mi ni Adeniran oruko baba to bi mi ni Adefarakan ti iṣe arẹmọ Ọba Adelẹkan (Olubuṣe).

Gẹgẹbi ohun ti Woli Aniyi sọ; lati igbati mo ti dagba to ẹniti o le ṣiṣẹ, ni mo ti ndupẹ lọwọ Ẹlẹda mi fun ibukun ati aponle ti Oluwa nfun mi ninu orisirisi iṣẹ ti mo ti nṣe kọja sẹhin ki nto wa di Oludasilẹ ati Alakoso ile iṣẹ "Ẹsan Kogbogun Service", ninu eyiti mo nri ikẹ ati igẹ Ọlọrun ninu rẹ titi di bi mo ti nkọ iwe yi ati wipe, mo tun dupe fun Ẹlẹda mi ti ojẹki nje ọkan ninu awọn ọmọ Yoruba ti o fara mọ ẹgbe oṣelu Ọlọpẹ, Afẹnifẹre, eyiti ko jẹki gbogbo ire aiye ti Olọrun fi da Ọpẹ l'ọla, ti o fi ju gbogbo igi ile aiye lọ ko fi jinna si mi.



ẸRUKOBODO

Adura mi si Olotu ati si gbogbo agbaiye ni wipe:—Gbogbo igba ti eni kọọkan wa yio ba lo ninu aginju aiye yi, ki Oluwa ki o jẹki a lo o pẹlu igbadun.

Ki Oluwa ki o da ẹmi wa si, ni aipẹ ọjọ ni itan igbesi aiye emi Ẹrukobodo yio han si ẹnyin onkawe. Ẹ ṣa ma a ka "Irohin Yoruba" deede, o digba kan na o.

"Ẹ hẹn! Eyi tutu gan...

Beer ati

Rose's

lime juice"

bẹ ni



Gbajumọ Afunfere ni Ibadan wi.

O ni:—

"Beer ati Rose's Lime Juice ni emi o ma mu lati isisiyi lọ. Gbogbo awọn ọdọmọkunrin ti nfun fere ni o si nmu pẹlu.

On gan ni o si tọ lati ma mu lẹhin ere aṣekara.

Lẹhin ti a ba ti mu, ere wa na nni arinrin ju bẹ.

Mọ pe Rose's Lime Juice ni o ngiṣẹ yẹn."

Iwọ sa tu Rose's Lime Juice diẹ sinu Beer rẹ, iwọ yio si ri pe iwọ nmu ohun ti o tu ni lara julọ ti o si nfun ni l'agbara julọ l'aiye yi.



Bere fun beer ati Rose's lime juice

## DA ẸJA TIRẸ SINU OMI



Eka Ile Iṣẹ Àgbẹ̀ ni Iwọ Òrùn ti nmu ojuto iṣẹ ẹja pipa nṣiṣẹ taratara lati ri pe awọn apẹja nri ẹja pa daradara. Idi eyi ni lati jẹki iṣẹ ẹja pipa ni ilọsiwaju nipa lilo ọna titun ti a fi npa ẹja ki a bale ri ẹja to fun ilera awọn enia ni Ipinlẹ Iwọ Òrùn. Kiko ẹja sinu odo ti Ẹka Ile Iṣẹ yi nṣe ti yọri si rere, bẹ na si ni iranlọwọ ti Ẹka na nṣe fun awọn agbẹ, ile-ẹkọ awọn Ẹgbẹ Alasowọpọ ati awọn enia omiran lati gbẹ́ omi ati lati ṣe itọju rẹ̀. Nisiyi irufẹ omi bẹ to wa ni Ipinlẹ yi jẹ marundilogoji, laika omi kékèké mejila omiran ninu eyiti ati mu oguta mọkanlelọgọrun ẹja jade ni ọdun 1957. Iṣẹ ẹka yi tun ni bakanna lati ma fi bi awọn ti npa ẹja lati inu ọkọ̀ kékèké han, lati mọ iye ẹja, lati ma da ẹgbẹ apẹja silẹ, lati ma ṣe iranlọwọ fun Igbimọ ti nya ni l'owo ni Ipinlẹ Iwọ Òrùn ati lati ma fi ẹ̀rọ p'ẹja ninu okun.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Òrùn Naijiria l'ó gbe ọrọ yi jade.

## Owe ilẹ Yoruba

Lati ọwọ Moses Ogunranti Akande, Iwo.

1. Ohun gbogbo ni o ṣe e fi sehin lọ, iwa ko ṣe fi sehin lọ. ibikibi ti a ba lọ ni o nba ni lọ.
2. Kota-kota (quarter weights) ni yio pa oni-koko, owo-ori ni yio pa oku-ọlẹ.
3. Nwọn bun ọ ni iṣu li Oyọ, o nyọ si i, o ti i ri igi fi se e na?
4. Enitì ti o nfi ojojumọ pe ara rẹ lọmode ki i mọ igbati agba kan on.
5. Ọjọ wo ni Arẹ kuna, ti o fi di ogun wipe a nse apejuwe rẹ ni ọkunrin kan?
6. Oju la a rọ, Ogo ko ṣe e ṣe.
7. Egan ni hẹ ẹ! ọlọmọ kan kuro ni kilo bi?
8. Agan obirin ti o ngbe ọmọ orogun rẹ jo, oju lo nro.
9. A ki i torọ ile sun ki a toro ile ku si.
10. Alara ni ngbe ara ga, bi adiẹ ba fẹ wọ ile ẹṣin, a si ma a bẹrẹ mole.
11. Oriṣa ni iwa, bi a ba ti mọ ọ hu si ni o se ngbe ni.
12. Oran fi ni dugbẹ dugbẹ bi ẹnipe ko ni i tan mọ, ọran yio tan, ọlọran yio si roko
13. Ikun nfẹ wa sile lati oko, Talomẹhin (ajaọdẹ) si mbẹ ni Bode, Owe olowo-ori ni o.
14. Alfagba fun ẹnikan ki i jẹk ile o gun.
15. A ki i lahun, ki a tun niyi, ọkanṣoṣo ni a nfọwọ mu.
16. Iregun yẹ alabahun, o si yẹ olugbo. Abahun ni Olugbo ko da aṣọ tuntun fun on, Olugbo ni, ti ọrun rẹ gbọ na?

## Awolọwọ Ni Badagry





* *

Aworan yi ni ti igbati awọn ara ilu Odibo fun Awolọwọ ni ẹbun ọbẹ ti nwọn si wipe ki o fi pa akukọ loju gbogbo enia.

* * *

Eyi ni awọn onilu kete ti nwọn wa fi ilu ba Ẹgbẹ Afenifẹre ṣe ipade ikede idibo ni ilu Agbadarigi.

*Ẹ ma a ka Iwe*
*IROHIN YORUBA*
*nigbagbogbo fun*
*irohin aladun*




# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣele larin ọsẹ yi lati November 22nd si November 28th.

## CAPRICORN
(Dec 21st-Jan 19th)

Wa a ri ninu ọsẹ yi pe nwọn fẹran rẹ pupọ. Bi ọkan rẹ ba wa lori a ntage, ni ọjọ Abamẹta ni wa ri nkan ti yio ṣẹ si ọ. Fi ara bale die ki o ri nkan ti yio ṣele larin ebi ki o to towọbọ "ṣoolo".

## AQUARIUS
(Jan 20th-Feb 18th)

Ọsẹ yi a mu irohin idunnu wa ti yio fa irin-ajo lẹsẹ. Ede-aiyede kekere kan a ṣele nibi iṣe re ṣugbọn ko ni pe tan nile. Ninu oṣu ti mbọ yi owo a tẹ ẹ lọwọ, asiko na a si dara fun ọ.

## PISCES
(Feb 19th-Mar 20th.)

Nkan iyanu kan yio ṣelẹ si o nipa ọrọ owo tabi ọrọ ẹbi. Lehin eyi, wa a gburo alejo ti wa fẹ yera fun un. Bi o ba fẹ ki nkan lọ daradara fun o ninu osu ti o mbọ ki o faramọ isoro die.

## ARIES
(March 21st-Apl 20th)

Osẹ pataki niyi fun iwọ alara ati awọn ti o ba da iṣẹ pọ. Enia kan a fi ọrọ owo lọ ọ ti yio dabi ẹnipe o fẹ mu ọ kuna. Ki o ri gbangba wipe ona tire to ki o to daradara ba enia towọbọ iwe-ajumọ-ṣe-pọ.

## TAURUS
(Apl. 21st-May 20th)

Wa a ri igbadun nibi iṣẹ rẹ larin ọsẹ yi. Pẹlu-pẹlu wa a le fi ori ọrọ nipa ile ati ọmọlẹbi ti sibi kan. Ma ṣe foya bi ẹnikan ti o ba fẹran ba gbe ọwọ iwa-abami kan tabi bi ọrọ-ifẹ nyin na ba ngmi.

## GEMINI
(May 21st-June 20th)

Ọsẹ a nṣe alejo ati a nṣe faaji ni eleyi. Wa a' rin irn-ajo kan, wa a tun kọwe senia kan ti gbogbo rẹ yio yọri si rere. Bi o ba nfẹ ki ere-iṣẹ rẹ gberi ki o gba imọran ẹnikẹni ti o ba wa niwaju rẹ.

## CANCER
(June 21st-July 20th)

Iru le ti ofẹ a tẹ ọ lọwọ tabi ki o ṣe nkankan ti yio mu ki ile rẹ dara si. Nipati owo, ọsẹ iyanu pupọ ni eyi, gbogbo rẹ lo si jẹ rere. Ma ṣe jẹ ki iponni nibi fajiṣiṣe ko si ẹ lori ki ọsẹ to pari.

## LEO
(July 21st-Aug 21st).

Ju gbogbo rẹ lọ iwọ na mọ ibiti o nlọ atipe bi igbesi aiye rẹ yio ti ri ninu Ọdun-Titun ti o mbọ. Enia kan ti o ti jẹ idina fun ọ ri yio pada di oluranlowo fun o larin ọjọ die. Idiwo-ile ti yio wa fun ọ koju lori owo-'na lori ile ati ebi lọ.

## VIRGO
(Aug. 22nd-Sept 22nd)

Ni ọsẹ yi owo yio wo'le fun ọ wa si le'pa ọja rira. Ninu nkan ọmọ'lebi iwọ na a ri pe o ki ṣ'enia kekere. Ki o ṣọ'ra pupọ fun adehun-titun ki ó si ma ṣe kọ'we omugọ si ẹnikan.

## LIBRA
(Sept 23rd-Oct 23rd)

Ninu ọsẹ yi, wa a ni ayọ-inu-didun ti o ko ti ni fun ọpọlọpọ igba. Gba eyi laiṣiyemeji nitoripe eyi yio ran igbesi-aiye rẹ lọwọ. Maṣe fọkan si ileri ti nwọn ba se fun o nipa owo ni ọsẹ yi nitori nwọn ko ni mu ṣe.

## SCORPIO
(Oct 24th-Nov 22nd)

Tete kọ ibi-ara si idiwọ ti o ba wa l'ọna rẹ. Eyi a ran ẹ lọwọ lati ta-kete si ọrọ-ẹgan. Owoti a wọle fun o a gbe-fukẹ diẹ, ṣugbọn a to ibẹrẹ oṣu miran ki o to mọ wipe o tiṣe-orire.

## SAGITTARIUS
(Nov. 23rd-Dec. 20th)

Nkankan a ṣe ni arinọsẹ yi ti a jẹ ki o yi ero rẹ pada lori igba ti mbọ. Bi o ko ba ni alabaro, idunnu mbọ fun ọ. Ṣọra rẹ pẹlu ọrọ-ẹgan ki o si yago fun ọrẹ oniwa-ibi.

# Ẹgbẹ Odozi

(Lati oju ewe kini)

nj'ẹ Nwiteshi, Mgbada ni adugbo umuezoka-Ezza ni Ẹkun Abakaliki larin oṣu kini si ekejila ọdun 1956. Ẹnikan ninu wọn, Ugozi Ofim, si tun gba idajọ iku fun pipa ti o pa ẹnikan ti o njẹ Nwonu Nsi ni adugbo Mbeke Isieke ni Ẹkun Abakaliki ninu ọdun 1957.

Kotu Giga, Enugu ko gba ẹjọ kotẹmilọrun ti ọdaran apania kan Michael Aniboro pe si Kotu na, lori idajọ iku ti Kotu Giga Warri ti ṣe fun un fun pipa ti o pa ẹnikan ti o njẹ EVWE ni adugbo Agbadu ni Ẹkun Warri ni ọjọ Keresimesi ọdun (1958) ti o kọja yi.

# Ẹgbẹ Oduduwa

(Lati oju ewe kini)

egbejila-dingọrun ponun (£12,300). Ọba Alaiyeluwa Erejuwa Keji, Olu Warri ati Oloye F F Ikomi si pe apejẹ lona meji fun gbogbo awọn Iko Ẹgbẹ ti o wa si ipade na.

Ninu ọrọ ti Dọkita Akinola Maja, Baba Ẹgbẹ Omọ-Oduduwa ti o ṣe Alaga ipade na fi kasẹ ipade na ni wipe, awọn dupẹ pupọ lọwọ Ọba Alaiyeluwa Erejuwa Keji, Olu Warri ati gbogbo awọn ara ilu Itshekiri patapata fun ayesi ti nwọn ṣe fun awọn Ikọ na. O rọ awọn ọdọmọde pe ki nwọn ma a ṣe otitọ ki nwọn si ma a tẹriba fun awọn aṣiwaju wọn, o si bẹ gbogbo awọn enia Ẹkun ilu Itshekiri pe ki nwọn ni ọpọlọpọ suru nipa bi akoko ti ṣe nyipada si.

Awọn arẹwa ọmọ-ge elere ilu Warri si bẹresi jo ijo iṣedale ilu Warri fun awọn ero ipade na. Ere ariya alarinrin ti nwọn tun fi yẹ wọn si, ti nwọn si nrohin rẹ kakiri ni ọkọ-aje Ọba ti nwọn fi njagun (Royal Regatta) ti nwọn di fi ṣe ere ariya fun awọn Ikọ na. O le ni edẹgbẹta ọkọ-ajẹ (500 canoes) ti nwọn ṣeloṣọ, ti nwọn si ta asia si wọn lara pẹlu ododo. Awọn ero ti o parọjọ si ibi ijoko awọn enia pataki-pataki l'ebute lati woran ere iṣedalẹ alarinrin na to ẹgbaamẹdogun (30,000) enia. Iru ere yi ni nwọn ma a nṣe ni ilara ni akoko ti nwọn ba fẹ ṣe ariya pataki bi iru ipade bayi.

Ki nwọn to bẹrẹ ere ọkọajẹ yi ni Ọba Alaiyeluwa Erejuwa Keji Olu Warri, pẹlu Ọba Alaiyeluwa Deji Akurẹ ati Ọba Alaiyeluwa Ebumawe Ago-Iwoye jijọ wọ ọkọ oju-omi kekere kan ti nwọn ti ṣe-lọṣọ dada lọ si Ode-Itshekiri (Warri nla) lati lọ ṣe etutu pataki kan nibẹ nipa Ajọdun na pe ki o le tu, ki o le ba. Ẹgbẹ na si ṣe ipinnu ni ipari ipade na pe, ni ilu Ibadan ni awọn yio ṣe pade ajọdun miran ti o mbọ.



